Consult:-
Baby West African Signwriter Companny
for your signwriting and Robber Stamp making —
4, Isalẹ agbẹdẹ St, Lagos Nigeria
(opposite Isalegangan Square.)

IROHIN IMOLẸ
MOTTO: IMOLẸ-DE, OKUNKUN PARADA.

Wanted
TO BUY
VACANT LAND
ANYWHERE IN
LAGOS 200 X 200
Call Personally:-
CROWNSON
16, Bamgboṣe- Street.
Lagos.

VOL. V No. 318 MONDAY FEBRUARY 26 — MARCH 4 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# IJỌBA DAJỌ AWỌN KANSILỌ TI KO SAN OWO ORI

Nile Ibiobio ni agbegbe Opobo ni ijoba ti ko ogunlogo awon Igbimo Ibile ti ko san owo ori won, Ajele agbegbe na, Ogbeni Ekanem, nigbati ori wipe enia pupo ni ko san owo ori lodun ni lo si Ipade awon Igbimo.

A tun ilu ṣe, a ni awọn Aṣoju Ijọba ilu. Nigbati o bere bi nwọn ba ti san owo ori wọn, ẹnu ya a wipe pupọ ninu wọn ko ti san owo ori wọn rara. Loju kan na o ṣe ẹtọ pẹlu wọn o si fa wọn le Ijọba lọwọ.

Ijọba da ẹjọ ẹwọn oṣu kọkan fun wọn, ti nwọn ko ba le san owo bi ọgbọn ṣile si apo Ijọba, lẹhin ti nwọn ba san owo ori tan.

Ọgbẹni Ẹkanem, Ajẹlẹ agbegbe na ni o ya on lẹnu pe awọn Oṣelu ni lati ma sa lati san owo ori ni iwọn igbati o jẹ wipe awọn ni nwọn nbu fun ẹlomiran. O ni on mura tan lati fi opin si iru aṣa jatijati bẹ.

## Faranse fe mo bi araiye ba le gbe ilu Orun

**Paris:— A ti gbo irohin bi awon Rosia ti se ran aja** ati ẹbọ lọ si Ọrun ti wọn si pada bọ, bẹ na ni a gbọ pe awọn ara ilẹ Amẹrika ran odidi enia lọ si Ọrun ti nwọn si pada bọ ba kan na.

Ṣugbọn a ti ri ka ninu iwe mimọ pe a koiti gbọ finrin, bẹni eti koiti gbọ wipe ẹda aiye kan goke lọ si Ọrun ri laye tabi ti o ti Ọrun sọkalẹ wa sile aiye ri. Eyi ni ohun pataki ti o mu awọn Faranse lati fẹ ṣe adanwo lati kọkọ fi ekute ransẹ si ilu kan ninu awọn Ọrun lati mọ bi ibẹ yio ba ṣe gbe. Awọn Faranṣe yio fi ekute nwọn ransẹ lọ si Ọrun ni ipari oṣu March 1962.

OKIGWE:- ọkunrin adamọdi Dokita kan ti ko kọ iṣẹ, ti ko si de ile ẹkọ ri, fẹ yọ arun ẹṣẹ kuro ni ọrun ọmọde kunrin kan, lo ba ge gbogbo iṣan ọrun rẹ, agbaregbabọ ọkunrin ti o ni arun na tẹri gba aṣọ. ni ibẹ ni adamọdi Oniṣegun na ba yinura sinu igbẹ, o si salọ bamu-bamu.

TAFAWA SO WIPE:-

## PELU AMUMORA, ATI SURU OHUN GBOGBO YIO SE SE

Ni ọsẹ ti o kọja ni Gbọgan Trenchard ni ile ẹkọ giga Univẹrsity ti Ibadan ni Alhaji Tafawa Balewa, Olori Ijọba Naijiria ti ba awọn ọmọ ile ẹkọ sọrọ atata. Ninu ọrọ rẹ, o sọ nipa lala ti awọn ti ṣe ki Naijiria to di Ominira o ni iṣẹ nla ti o wa niwaju gbogbo wa nisiyi ni bi a o ṣe lo Ominira na fun ogo ilẹ wa ati itura awọn enia wa. Oni Ṣugbọn o da on loju pe bi a ba le ma ṣe suru nigbati ọrọ ba diju, ti a si nni amumọra, ohun gbogbo yio ṣe ṣe.

O ni ki awọn akẹkọ na sọra ki awọn Oṣelu ti ko bikita fun irẹpọ ma, tọ wọn si ọna ti ko yẹ.



TAFAWA BALEWA LO ṢE ALAGA NIBI IPADE AWỌN OLOTU IPINLẸ MẸTẸTA NAIJIRIA NI ILU IBADAN.

Gbogbo awọn Olori Oṣelu ti o mbẹ ni ilẹ Naijiria, awọn bi Oloye S. L. Akintọla, Dokita M. I. Ọpara, Sardauna Sokoto ati Tafawa Balewa pẹlu awọn isọngbe wọn ninu awọn Alaṣẹ ṣe ipade nla kan nigboro ilu Ibadan, Alhaji Tafawa ni o ṣe Alaga Igbimọ, Alaiyeluwa Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun lo si ipade na. Tafawa Balewa lo duro ti nsọrọ ninu aworan oke yi, Gomina Ibadan si nwọ li ẹnu. Akintọla lo joko lẹgbẹ Balewa.

# ORO OLOTU

## E fi Apere rere lele

NI OJU KINI IWE WA NI IROHIN AWỌN OṢELU TI KO DA OWO ORI WA. O YẸ KI EYI JẸ ITIJU NLA-NLA FUN GBOGBO WA.

Bi awọn ti a gbe ilu si lọwọ ba jẹ arufin bawo ni nwọn yio ṣe le fun ilu ni ofin ti o tọ? Bawo ni nwọn yio ṣe le tun ilu ṣe?

Ni iwọn igbati awọn Oṣelu ti o nbu owo ori ko ba san tiwọn, bawo ni ẹ ṣe ro pe mẹkunu ti o mọ pe ẹ ko san yio ṣe san.

Orọ yi ki ṣe ti ilu Ibiobio nikan. Ibi gbo-gbo lo wa. Pupọ ninu awọn Oṣelu wa ni ki isan iye owo ti o yẹ ki nwọn ma san. Pupọ ni ki isọ iye owo ti o nwọle, bẹni ẹnyin ni ẹ nṣofin, bẹni ko si ohun ti a le ṣe laisi owo ori.

Ẹ fi apẹrẹ rere lelẹ, ẹ jẹki a ri nyin, Ẹ yọ iti oju ara nyin ki ẹ ba le yọ ti mẹkunu.

## Nwon dite lati da oko Omoba Mragaret duro lenu ise

Inunibini ko kan-kan alaimọ iwa wu, ṣiwaju ki Antony to fẹ iyawo rẹ, Ọmọba Margaret, fọto lo nya kakiri fun iwe irohin kan ti a npe ni Sunday Times. Iṣẹ yi na lo nṣe ki o to ba Margaret ọmọba ilẹ Gẹsi sọrọ ifẹ pa pọ, ti nwọn si ba ara wọn gbeyawo A r e de.

Gẹgẹbi aṣa Gẹsi ẹnikẹni ti o ba fẹ ọmọba Ọba Gẹsi ni lati da Oluwa rẹ ni ọla, ko da bi oluwa rẹ jẹ akuṣẹ, Ọba yio sọ di ẹni nla larin ilu. Eyi ni idi rẹ ti nwọn ṣe fun Antony ọkọ Ọmọba Margaret ni oye L o r d Snowdon nwọn si fun ni aṣẹ lati ma paṣẹ lori afin Nlanla kan. Inunibini ko kan aimọ iwa hu rara. Eyi ni Okunrin Olowo arakuyanu ara ilẹ Kanada kan ri tobẹ ti o fi nleri bayi pe On ni lati ri wipe on da ọkunrin ti nwọn npe ni Lord Snowdon yẹn duro lẹnu iṣẹ laisi ibere kan wipe kiloṣe. Kosi ẹniti o le yẹmi lọwọ rẹ wo, ṣugbọn bi o ba jẹ pe dida duro ti mo da ọkunrin na duro lo ko wahala ati inira ba Idile Ọba, ngo mu ọwọ kuro ninu ohun ti mo fẹ ṣe na, nitoripe nko fẹ inira kan Idile Ọba Gẹsi.

## Olopa mu Kehinde wa lati Ilu Oyinbo

Ni ọsẹ ti o kọja ni Kẹhinde Collins ti o lẹ si ilu Ọba ni ẹgi fun ẹkọ de pelu Ọlọpa oyinbo kan lẹhin rẹ Nigbati a-rabirin yi de ilu Ọba awọn Ọlọpa yẹ ẹru rẹ wo, nwon si ba Igbo ti nwọn ma nmu bi siga ara binrin yi ni o ni obinrin kan ti oruko rẹ ojẹ Angelina Johnson ni o fi ran on si Omọ rẹ ni Ilu ọba Nwọn mu de ile Ejọ Ṣugbọn wọn da silẹ,

Lẹhin eyi ni Ijọba Naijeria mu ẹniti o fi Igbo ran kẹhinde ọlọpa Oyinbo si mu u wa ni-nyi lati jẹri pe nitotọ ni Johnson fi Igbo ran-ṣẹ si Ilu Ọba,

Ijọba ko gba ki Kẹ-hinde ba awọn enia rẹ gbe titi yio fi ṣe ẹlẹri ti o fẹ ṣẹ ki o to pada si Ilu ọba lati lọ ko ẹkọrẹ

## ỌKUNRIN ONIJIBITI KAN SE WAYO O SI WẸWỌN ỌDUN MEJI

IBADAN:- Ọkunrin kan ti n w ọ n npe ni Alhaji Muhamadu ko nṣe wipe, o de Mẹka ri, oruko rẹ ri Alhaji, iṣẹ wayo ati jibiti lo nṣe kakiri.

Ọkunrin miran ti o njọ Salu Yaro ni elarọ-na fun Alhaji Muhama-du yi, o wa lọ rohin iru iṣẹ ti Alhaji na nṣe fun ọkunrin Ibo kan ti wọn npe ni Job Igbojọenu, wipe, Alalupaida ni Al-haji na bi enia fun ni ẹgbẹrun pọnun, yio sọ di ẹ g b a a pọnun fun oluwa rẹ. Ara J o b bu mọ aṣọ lo ba lo tu owo ti o wa ninu ile jọ, o ri pọnon mẹrila di ni adọ-rin ko jọ, o si ṣeleri fun Job pe on yio sọ owo na £286 di £2000.

Odabi ẹnipe nṣe ni Ọkunrin Salu Yaro ati Alhaji yi wa fi abo bo on loju, ko pe ti Job ko owo fun onijibiti yi tan, lowa dabi ẹnipe nkanna ka kuro loju on.

Job sọ pe nigbati nkan na ko kuro loju on ti on si lọ bere owo on pada, ija ni Alhaji gbe ko on ti o si yọ ọbẹ lati pa on, Adajọ ri pe ẹjọ Alhaji ti jẹbi, o si paṣẹ pe ki o da owo to gba pada ki o si lọ si Ẹwọn Ọdun meji.

## Aworan Asikiwe ni ile-iwe giga ti Methodist Boys High School nilu Eko



Ni agogo mọkanla abọ ni owurọ ọjọ Tuesday ti o kọja ni n w ọ n ṣe ẹyẹ ṣisi aworan Ọlọla Asikiwe, Gomina agba fun ilẹ Naijiria si. Ile iwe g i g a ti Methodist Boys High School ni Eko, ninu ile ọkọ yi ni Ọlọla Asikiwe ti ka iwe, ẹniti o si fi aworan na ṣe ẹyẹ fun ile iwe na ni Ọgbẹni Adeniyi Coker ọkan ninu ọmọ ile iwe yi na ni Ọgbẹni Coker nṣe.

Ọlọla H. O. Davies li o sọrọ nibi ẹyẹ na. Oloye Davies papa jẹ ọkan ninu awọn ti wọn ti jijọ nkawe ni ile iwe yi pẹlu Gomina agba. Oloye Davies ni aworan na y i o jẹ igberaga fun awọn agba ti nwọn ti ti ile iwe na silẹ, yio si jẹ iwuri fun awọn ọmọde ti o wa nibẹ nisisiyi wipe, enia Dudu ti o kọkọ joye Gomina Agba nilẹ yi, ninu ile ọkọ wa yi ni Methodist Boys High School lo gbe ka iwe rẹ jade

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Enia lo nleni debi Ola Eni

LATI ỌWỌ:— FATAI A. OYERỌGBA
NO. 18, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

O ṣe ni ilu kan, Ọba kan wa, o ni Ọla pupọ, o ni Iyi pẹlu, o si bi ọmọ binrin ti o dara kan ti o jẹ pe ninu gbogbo ilu yi, ko si ẹniti o dara to ọmọ Ọba yi. Nigbati o to akoko lati lọ si ile Ọkọ, awọn Ijoye ti o wa ni ilu wa lati wa tọrọ ọmọdeyi, bi Ijoye ti nwa, bẹni Ọlọla nwa lati fẹ ọmọdeyi, ṣugbọn ọmọ yi kọ jalẹ pe on ko fẹ ẹni kankan. Agbẹ kan wa jade lati lọ tọrọ ọmọ yi, ọmọde binrin yi gba lati fẹ Agbẹ aroko yi. Ṣugbọn Ọba binu gidigidi pe, laduru gbogbo awọn Olowo, Ọlọla ti nwọn nwa yi, Baba Aroko lo wa fẹfẹ?

Ọmọde yi kọ jalẹ, o ni on ni on yio fẹ, Ọba pinnu pe ki o kuro ni ilu fun on, Baba Alagbaro yi ni, nitori pe on mafẹ Iyawo ki on wa fi iṣẹ tabi ilu ti on ti njẹ, ti on ti nmu silẹ, ki on kuku ma fẹ ọmọ yi mọ. Ọmọ binrin na gba pe ibiti enia ma de ni aiye, koni sayi debẹ.

Ni owurọ ọjọ keji, wọn bẹrẹ irin ajo wọn, wọn rin titi, Baba Alagbaro yi daku si oju ọna, Ọmọba yi joko ti Ọkọ rẹ, o bẹrẹ si sọkun, Ọdẹ kan wa ni to si ibẹ, o ngbọ ẹkun enia, o wa jade sita gbangba, o ri niti o nkigbe, o bi lere pe kini o de si iwọ arabinrin yi? lo ba ko ọrọ o ro fun, Ọdẹ yi ba dahun pe, on yio ji Ọkọ rẹ Alagbaro yi, Ọdẹ yi mu ileri rẹ ṣẹ, o ji Alagbaro yi, nigbati o ripe o ti nsọrọ, o wa sọ fun Iyawo Alagbaro yi pe, mo fun yin ni ọmọ mi obinrin yi lati fi ṣe ikeji rẹ lati tọju Ọkọ yin. Ọdẹ yi tun sọfun Alagbaro yi pe, ilu ti o nlọ yi, nwọn ki wọbẹ ni owurọ ayafi asalẹ ti o ba dẹ fẹ lọ, oru ọganjọ ni ki ẹ ti mura lati lọ, ti ilẹ ba mọ ba yin nibẹ, wọn yio pa Ọkọ yin, Ẹ o di Iyawo Ọba, wọn mura si irin ajo wọn, wọn nlọ, wọn de ilu na ni alẹ, ile Ọba ilu na ni wọn de si, wọn ṣe wọn ni alejo, ninu awọn ọmọ Ọba ti o ngbe onjẹ fun wọn nsọ wọn.

Nigbati asiko ati sun to, wọn teni fun wọn, ọmọ Ọba binrin yi wa lọ ba Baba Alagbaro yi, o ni o wu mi ki nfi ọ ṣe Ọkọ, ati pe nwọn yio bere ibere mẹta lọwọ rẹ, ti iwọ ba yege, wọn yio fi ọ jẹ Ọba dipo Baba mi, ti iwọ ko ba mọ, nwọn yio pa ọ. Wọn yio bere pe kini ohun ti o wa ni ile ọwọ ọtun, ọwọ osi ati ile ọkankan? Bi o ba ti mọ, o yege ni yẹn.

O bere lọwọ ọmọ na bayi pe, bawo ni emi yio ti ṣe mọ ki ilẹ ọla to mọ, ọmọbinrin yi wi fun pe, ile ọtun yẹn, ẹru Ọba lowa nibẹ, Ile osi yẹn, Ẹru awọn Ijoye ni Ile arin yẹn ko si ikan kan nibẹ, ọdẹ yi dupẹ pupọ lọwọ rẹ o ba ṣe adehun pe on yio fẹ ọ. Ilẹ ọjọ keji mọ, wọn pe alejo yi wa si Afin gẹgẹ bi ohun ti wọn ma nṣe ati ibere ti wọn ma nbere lọwọ alejo ti o ba wọ ilu. Awọn Ijoye ti peju, Olowo, ati Ọlọrọ ilu pejọ safin Ọba.

KO ITI PARI

## Aja Wasuku lo be ilu Oyinbo wo



Nigbati Ọgbẹni Aja Nwaṣuku lọ ṣe abẹwo ilu Gẹsi, o ya lọ wo gẹgẹ bi awọn ọmọ ile Ẹkọ ti nṣiṣẹ wọn si ninu ile ẹkọ kan ti nwọn npe ni Elthan Green nilu Oyinbo, o si ba awọn ọmọ wundia meji ti orukọ wọn njẹ Amelia Gilliet ati Gillian Parson ọmọ ọdun mẹtala ti nkọ bi a ti ṣe nya aworan.

## Kini ohun ti o mo nipa awon Alase ile Naijiria?

(1) Ilu wo ni a ti bi ọlọla Amadu Bello Sadauna of Shokoto?
(2) Ọdun wo ni a bi ọlọla Jaja Nwanchuku.
(3) Ninu ọdun wo ni a yan gẹgẹbi alaṣẹ eto ẹkọ fun Ijọba apapọ ilẹ Naijeria
(4) Ọdun wo ni wọn da ẹgbẹ Olomi Northern People Congress silẹ.
(5) Tani o da ẹgbẹ na silẹ.
(6) Tani oludasilẹ ẹgbẹ ọmọ Oduduwa,
(7) Tani a bi ni ọdun 1912 ninu awọn oṣelu Naijeria
(8) Ọdun wo ni a bi ọba Adeniji Adele
(9) Ile Ẹkọ giga wo ni Ọba Adele lọ,
(10) Ọdun wo ni wọn ṣi iga Idunganran titun ti ijọba apapọ kọ fun Ọba eko.

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌN YI NI OJU EWE KEJE


# Yoruba Challenge

## March - April 1962

TI JADE FUN TITA

O kun fun ẹkọ Ajinde, itan ati irohin.

Awọn aworan inu rẹ fanimọra.

Oju Iwe rẹ pe 24. Tete ranṣẹ tirẹ.

4d pere fun Iwe kan.

# O ya ti NCNC yio kuro ninu Ijoba

Lati Owo:— Afolabi Olabimtan

Enu ma n y a mi pe, Olola Opara, Olori egbe Alakuko ko nmo iwon ara re. Bi o ba mo iwon ara re ni a mo pe ni ile Naijiria lode oni, Hausa ni alagbara, ohun ti njw oln ba si fe ni egbe re ni lati fe.

Nigbati Opara gbo pe AG fe darapo se Ijoba, o ni on ko ni ti owo si i, bi e n i p e o ni agbara lati tako iru ero bayi, O gbagbe wipe on papa ati egbe on, lowo anu Alhaji Tafawa lawon wa, ti o ba si ti te Alhaji lorun bi Opara fe bi ko fe sise ni.

Boya Opara ko mo pe nisisiyi NPC ti ni omo egbe to ni ile isofin nla lati se Ijoba l a i pe egbe on. Bi o ba gbon, ki o ya pa enu re mo ki o ma se se Alhaji Tafawa Balewa ki o ma ba le won jade.

## Awon Oyinbo Onisowo U. A. C. fi m o t o alarun tore fun I j o b a Sabarumo

U. A. C.:— Irohin ta si wa leti pe awon Oyinbo Onisowo U. A. C. fi moto ti o ngbe awon ti o ba fi a r a gbogbe alaisan, tabi awon A l a r u n (Ambulance) lo s i l e iwosan ta Ijoba Sabarumo ( M a l i ) l o r e, Oyinbo U. A. C. to gbe moto na lo fun won ni Ogbeni Wallaston, o si fi le awon ijimi enia nwonyi lowo: Jean Marie Kone, Minister, Alasane Haidara, Somine Dolo, Mousa Keinta.

PALM LINE:— Oga oko W. G. D. Keill ti o ti nsise Ogako labe awon Oyinbo Oloko Palm Line f u n odun merindilogbon ni a gbo pe, o ti fi ise sile, on lo sise ninu oko M. V. Lobito Palm gbehin.

Awon omode nwonyi ni a gbo wipe awon Oyinbo U. A. C. f u n ni ebun eko olofe, oruko w o n ni wonyi:— Emmanuel omo odun metala y i o lo kowe ni M. B. H. S. E k o, Fasasi je omo Agbowoka kan ni Oshogbo, yio lo ko eko re ni Grammar S c h o o l Abeokuta. Jubrila omo odun merinla yio lo ko e k o tire ni Ibo U n i o n Grammar School ni Kano, Raphael omo odun merinla yio lo ko eko tire ni National Grammar School Enugu, Felix omo o d u n merinla yio lo ko eko tire ni St. Patrick College Asaba.

## Awon adete ko lati pada si arin awon Ebi won

ABAKALIKI:- A gbo irohin wipe, awon Adete po gidigidi ni ilu Abakaliki, Ijoba si ko ilu kan fun w o n ni biti awon enia na yio ma gbe ti arun ete ko fi ni ran mo enikeji, nwon npe ago awon a d e t e na ni Segregation Leper Camp.

Lakoko ti nwon ba wo enikan san tan, awon Onisegun won ati Alakoso won, yio fi ase fun won pe, ara won ti da, ki won ma lo sile won, sugbon lodun ni a gbo wipe awon ti won da sile ninu awon Adete wonyi po tobe ge, to fi je wipe enia die lo tun ku ni i b u d o Adete ni Abakaliki.

## Awon Anti-Palor ti o nsise ninu Oko Ofurufu



Awon marun ti nwon we gele ninu aworan yi ni awon Obinrin ile Naijiria ti awon Oloko ofurufu gba lati ma se Anti Palo fun awon ero ti o mba oko ofurufu lo si ilu Oyinbo, ilu Meka, Amerika tabi awon ilu miran lona Oke okun. Oruko won niwonyi:—

Awon ti nwon duro ni Victoria Doyle lowo osi, Rita Lester, omo ile Gesi ni sugbon Eko lo ngbe nisisiyi, on lo wa larin meji won, Christie Okoro omo ilu Oweri.

Awon to joko lati owo osi, Sinyelu Agu omo ilu Obosi, Rose-Mary omo ilu Eke ni Enugu eniketa won ni Dorothy Agina omo ilu Onitsha. Gbogbo won si mbe lenu ikose lowo.

## Awon Asoju ninu Ipade gbogbo Agbaiye



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Asoju ninu i p a d e gbogbo Agbaiye eyi ni aworan ti won ya nigbati won nse ipade na lowo ni ilu Londonu, won duro won si fi oro jomitoro larin ara won, oruko won ni wonyi:— lati owo osi, Olola R. A. Njoku, A l a s e eto oko fun ile Naijiria, Olola L. H. Shantz, eni owo Earl De Lawarr, ati Ogbeni L. H. E. Bury, Olori Asoju ile Australia.

# Aseju ni Baba ese, Ese si ni Baba Adanu

Lati Ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Ibinu ko yẹ ọmọ enia, nitoripe ninu ibinu ni ẹṣẹ ti njade wa, Ibinu abiju ẹṣẹ lo nmu wa ninu ibinu ni ipinya ti nwa. Ẹ jọwọ ẹjẹka ṣọra fun ibinu, ibinu aṣeju lonpania, Ẹnikẹni to ba jẹ Imale Ododo tabi I g b a g b ọ Ododo ki ibinu beni ki sise aseju.



WOLI KOGBEREGBE

Nitorina mo fẹ ki ẹ mọ wipe ẹnikẹni to ba nja B a b a tabi Iya rẹ li ole ti o si wipe ki ṣe ẹṣẹ on na ni ẹgbẹ apaniruo, Ẹniti o ṣe agberaga li siya, a ru ija soke ṣugbọn ẹniti o gbẹkẹ rẹ le O l u w a li a o mu sanra eniti o gbẹkẹle aya ara rẹ asiwere ni.

Ṣugbọn enikẹni ti o ba nfi ọgbọn rin on li ao gbala OWE 28 ẸSẸ 24, Ẹ jẹ ka ṣọra ni nu iwa aṣeju. Bi iwọ ba jare ọrọ rẹ aṣeju yie si mu ọ jẹbi ọrọ na, oju yio si ti ọ nitori aṣeju rẹ.

Ẹnikẹni ti o ba pa Ofi mọ on naini yio ri Iye ainipẹkun lati ọdọ, Ọlọrun, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ru Ofin yio jẹ gbese, ki yio si ri ran lailai, nitorina ẹjẹ ka sa fun ẹṣẹ.

Ẹ jẹka fi ẹṣẹ silẹ, Oluwa tirẹ ni Ododo, ṣugbọn ti wa ni Itiju, DANIELI 9, Ẹ S Ẹ 7. Ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ wipe ere ajẹju koyẹ ọmọ Ọlọrun, nitori ọrọ ẹlẹtan enia ti pọ si Orilẹ-Ede Ẹ jọwọ aseju ko dara, bi enia nṣe aṣeju yio pofo Ha! awọn ọmọ araiye yio si ma wi loju rẹ pe jọwọ musuru maṣe binu si aya rẹ tabi ọmọ rẹ.

Ṣugbọn bo ba di ẹhin rẹ tan, nwọn o si ma wipe, ko ha tan bi, ko mọ pe aṣeju lo npania, Aṣeju to fi le gbogbo Iyawo rẹ lo na ni yẹn o, Ero ibi si ni ero wọn, Ẹ maṣe jẹ ki ẹnikan ki o ro ibi ni ọkan rẹ si ẹnikeji rẹ ẹmaṣe bura eke nitori wipe gbogbo iwọnyi ni mo ko rira ni Oluwa wi. SEKARIAH 8, ẸSẸ 17 Ohun rere kan ki dun nitori ti o ti fi aṣeju bọ inu rẹ Aṣeju lonsọ ohun didun di kikan, nitorina ẹ maṣe fi ohun Mimọ fun aya ẹ ma si ṣe sọ perli yio siwaju ẹlẹdẹ nwọn asi yi pada ẹwẹ nwọn a si bu yin san MATTEU 7, ẸSẸ 6. Aseju ko dara rara, aseju ni awọn ole nṣe ti wọn fi ko si ọwọ Ọlọpa, ṣugbọn mo fẹ ki ẹ mọ pe ohunkohun ti aṣeju ba ti de, yio bajẹ ni, ko si ni, ni atun ṣe mọ. Aseju a ma le ohun rere jina si enia, aṣeju ni Baba aṣetẹ.

## Ololo Njoku lo se abewo Apapa



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni igbati Ọlọla B. A. Njoku lọ ṣe ayẹwo awọn ẹrọ ti yio ma lọ awọn iyẹfun ti a fi nṣe burẹdi ti nwọn si kọ ile ẹrọ na si eti Idiko ni Apapa. Ọgbeni G. P. Coummantator ni yio ma ṣe alamojuto ile iṣẹ ibiti a gbe ti nlọ yẹfun na.

## Iyan Omi lo mu Omo ilewe kan ku si Odo Oya

AWKA:- A gbọ irohin wipe, omi wọn ni agbegbe ilẹ Onitsha tobẹ ti nwọn fi nta G a r a w a omi kan ni Ṣile meji, awọn ẹlomiran ti ko le fi ara da lati san Ṣile meji fun Garawa omi kan ran awọn Ọmọ rẹ lọ si okan bi busọ meji lati lọ pọn omi ninu odo igbo.

Ni akoko na ni Ọmọ ilewe ti nwọn npe ni Felix Okafor wa omi lọ sinu odo Oya lati lọ pon omi wa si ile, ṣugbọn nigbati o de ọhun, o bẹrẹ lati pọn omi ni ẹsẹ rẹ ba yọ lori Apata, o si ba omi lọ.

Ọmọde na jẹ ọmọ Akẹkọ Ile ẹkọ giga ti nwọn npe ni Totre Dame High School ni ilu Abatete ni agbegbe Onitsha.


**Are you also Suffering Silently from:-**




TIRED OUT WITH CONSTANT PAIN LIMBS LIKE PIECES OF LEAD BACK-ACHING SWOLLEN JOINTS SHARP SHOOTING PAINS LUMBAGO, RHEUMATSM - GOUT — ARTHRITIS

Millions of people are suffering under these terrible affliction which constanly impair with the meeling of health THE CAUSE?- EXCESS OF URIC ACID IN THE BLOOD. THE CURE?- UROXAL. The kidneys must be prompted to cleanse from the system the pain-giving heart affecting poisons and this on the evidence of thousands of one-time sufferers restored to normal health condtions by the use of **"UROXAL"** the World reknowned remedy for all Kidney and Bladder affections.

*Price 8/6d Postege 2/6d.*

(MADE IN FRANCE)

Stockists:

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

## IYAFIN ALAKE OWON:

# Oko Ale mi ko gbogbo aso mi lo.

IBERE:- Mo jẹ ọkunrin ti ọjọ ori rẹ to Ọdunmọkandinlọgbọn, mo si yan ale obinrin kan ọmọ ọdunmẹtadinlogbọn nibi kanna ni a ti gbe jijọ nṣiṣẹ, nilu wa, asi ma ri ara wa lojojumọ, Ni igbamiran ọwẹ emi a ma sin lọ si iletaja lati lọ ra nkan ni ṣọbu. Mo fẹ ran Obinrin yi ju Igbesi aiye mi ati awọn Obi mi lọ. Nkan ti o wa ṣoro ni bẹ ni wipe mo ti gbeyawo, on na si ti ni ọkọ, o sọ fun mi wipe on fẹ ran mi ju ọkọ on lọ, gẹgẹbi o ti ni fẹ mi to, o ma wa ba mi fọ awọn aṣọ mi ti o ba doti o ṣe ni ọjọ kan nigbati o wa ba mi fọṣọ, ọkọ rẹ wa si bẹ o ri nibiti o gbe nfọ aṣọ mi o lu u, ni aludojubolẹ o si ko gbogbo aṣọ mi ti o mba mi fọ lọ si ile rẹ.

Nisisiyi emi ko mọ ohun ti emi ko ba ṣe boya ki nkọ aya mi silẹ ni tabi kini ki nṣe? tabi ki lọ ba ọkọ alẹ mi na ja ija nla.

ILARO ADISA KASUNMU

IDAHUN:- O titọ lo nsọ nkan wọnyi, Ṣugbọn ki o lọ ba ọkọ lo koji rẹ ja tabi ki o le aya rẹ lọ, ko ṣe nkan fun ọ Ni ọna akọkọ o yẹ ki o ba ara rẹ wi pupọ nitori aya alaya ti o lọ ba, ti o si fẹ ji ifẹ enifọ gbe. Iru nkan buruku bayi ni o ma gbẹhin ẹniti o hu irufẹ iwa yi. Nkan ti o dara ju pe ki o ṣe ni pe ko gbagbe gbogbo rẹ, ki o si wa iyawo tirẹ lọ, eleyi yio si yọri si rere fun ọ jupe ki o ma lọ ba aya ẹlomiran lọ.

IBERE:- Mo nfẹ ọmọbinrin kan, ọmọ na si nfẹ mi, ṣugbọn gẹgẹbi aṣa ilẹwa mo mu ọmọ na lọ han Iya mi mo tun lọ fi ara mi han si iya ọmọ na ṣugbọn iya rẹ taku wipe rara on ko ni fun mi ni ọmọ on,

Gbogbo owo ti mo ti na fun ọmọ na lẹsẹkẹsẹ ni wọn ti da pada fun mi, ni ọmọ na na Babẹrẹ si sọkun pe dandan emi ni on yio fẹ, emi na si taku pe on ni emi na yio fẹ ki a ma fa ọrọ na gun wọn da ifẹ wa ru, Ki Ọlọrun mase da ifẹ wa ru, Ọmẹ wa na ranṣẹ si mi wipe ki nfi ọkan balẹ emi sa ni on yio fẹ dandan, Awọn Obi temi si ti sọpe ki wa yawo miran lọ Iyafin Alakẹ ewo ni ki nse o, Ọmọ Taku pe on yio fẹ mi Awọn ile wọn kọ Iya mi na ni ki nwa miran lọ ọmọde sọpe afi ọri afi ọrun, Ewo ni ki nṣe o.

ORO TOWN S. ONIGEGEWURA.

IDAHUN:- Mi si ibere ọgbẹni S. Onigegewura niyi Awọn Yoruba mọni mọni lo npa owe bayi wipe, Iyawo buruku ko ṣoro ni fifọ, ana buruku ni ko sunwọn lati ni. Nigbati ọmọbinrin na taku wipe, a fi ori a fi ọrun, ayafi bi on ba fẹ Onigegewura, ti on paapa si wipe, bi igi nlugi mọ igi ọmọdebinrin na ni on yio fẹ ṣugbọn Iya ọmọ na kọ lati fi ọmọ rẹ fun ọ, bẹni awọn Obi tirẹ paapa ko lọwọ si pe ki o fẹ ọmọ na.

Imọran mi si ọ ni wipe, ki o fi ọmọ na silẹ ki o si wa omiran lọ, Ki Ọlọrun mase jẹki ohun ti yio pu wa wu wa, Bi enia ba ti nṣe ohun kan lọ, ti gbogbo rẹ ngun regerege, ti o si tun wa ri ohun ikọsẹ sakiyesi pe nkan na ko ni ṣe on lanfani lo jẹki o ribẹ.

Fi obinrin na silẹ ki o wa ọmiran lọ, nitoripe enia ko le ri iku nilẹ ki o lọ tẹ ọrun bọ.

Emi ni:- Iyafin Alake

# Iya, Omo ati Baba ku lehin onje

Ni Oroga, Ileto kan ni Ondo ni ariwo ta ni ọsẹ ti o kọja nigbati arakunrin kan Ajijọla Onipẹde, iyawo rẹ Alice ati ọmọ wọn ku lẹhin onjẹ ti nwọn jẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, Olu ti Ajijọla mu bọ oko ni nwọn se ni alẹ, eyi ni nwọn si jẹ tan ti inu bẹrẹ si run gbogbo wọn. Awọn ero ileto na gbiyanju lati ran wọn lọwọ pẹlu ẹro inu ṣugbọn ẹpa ko ba oro mọ.

Ki ilẹ ọjọ keji to mọ gbogbo wọn ti ku.


# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ọ lọkan je, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilọ nṣiṣẹ na owo lọọ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kona.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MỌLẸYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERA



# Akiyesi Pataki

MAṢE SURE LỌ YO "EHIN" ENU - RẸ MỌ NITORI IRORA "AKOKORO" LAI DỌN EGBOGI TITUN TI WỌN NPE NI:—

TOOTH  LINIMENT

YI WO KI O MA BA KE ABAMỌ O

Gbogbo awọn ẹniti AKOKORO nyọ lẹnu mọ bi oro tabi Irora rẹ ti pọ to, pupọ ninu awọn enia wọnyi a si ma lọ yọ awọn EHIN ti o fa Akokoro yi wa bawọn kuro ki wọn leri alafia. Nipa yiyọ omiran ninu awọn EHIN wọnyi, a ko ba Oju ati ẹrẹkẹ ẹlomiran a si papọ wọn a si wa di arugbo eku, pẹlu.

O ṣe enia ni anu lati ri wipe Pupọ ninu awọn egbogi ti a nta kakiri Igboro fun Akokoro ko ti ẹ le ṣe iwosan rẹ rara, de bi ti yio le pa kokoro buruku ti o njẹ EHIN ni idi, tabi erigi nitoripe wọn ko lagbara to rara lati le de ibiti kokoro yi gbe sapamọ si.

Aworon ti oke iwe yi fi han ọ daju gbangba bi EHIN rẹ ti ri de isalẹ atipe awọn egbogi lasan tabi olowo poku ko le ṣe iwosan rẹ daradara. Nitorina a gba ọ ni imọran wipe ki o rọju nigbakugba ti Akokoro ba nyọ ọ lẹnu lati ra tabi ranṣẹ lọ ojulowo, giriki ati egbogi rẹ ti a asesẹ wa idirẹ kọn ti a npe ni TOOTH LINIMENT ki o dọn wo larin iṣẹju marun pere iwọ yio ri gbangba daju pe "Meji" rẹ kosi fun akokoro ni gbogbo ilu Naijiria iyẹn daju.

Ki o to lọyọ EHIN rẹ, masalai dọn Egbogi yi wo bi bẹ kọ iwọ yio ke ABAMỌ. IṢẸ rẹ daju. A si lẹ ẹnyin onibara wa gbogbo ni Ariwa ati Gusu lati ma rohin Egbogi yi fun awọn ẹlomiran niwọn igbati ẹ ba ti lo wo ti ọ si ba bi ati rohin rẹ pẹlu.

SILE MEJI PERE Postage 1/3d
DỌZINI 20/- POSTAGE & PACKING 3/-

A si tun ni awọn Egbogi fun oju didun tabi ọna ọfun ti owo wọn roju fun tita pẹlu ni orişirişi.

Bere ni Ṣọbu awọn:-

## Waterloo Medicine Stores

8, Palmchurch Street, P. O. Box 333
LAGOS NIGERIA W. C. A. Phone 22878.

Akiyesi:- Ṣọra ki awọn ẹlomiran ma fi eru ta adamọdi fun ọ o.

# Dr. Okpara wa si Ipade ti nwon se ni Ibadan



Nınu ipade kan ti awọn asiwaju awọn oṣelu ipinle Iwọ Orun, Ila Orun, Ariwa ati Ijọba Alapapọṣọ ṣe nigboro ilu Ibadan lati jumọ ni ajumọsọ nipa gẹgẹbi nwọn o ti ṣe ma na owo. Ẹniti o ṣe Alaga Igbimọ na ni Ọlọla Alhaji Tafawa Abubakar Balewa. Ẹniti o si si pade na ni Ọlọla Adesoji Aderemi. Ẹniti a nwo ninu aworan yi lọwọ ọtun ni Dr. M, I. Okpara, nitori ou jẹ ọkan ninu Igbimọ na.


## MOGBAYI BABY MIXTURE

### OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ti a se ni ase pe fun awọn Ọmọde ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribi ribi ti o ti nṣe.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara fun igbona, ikọ, otutu A i p e r i, Osi Ọmọde, jedijẹdi, kokoro ori Ọmọde. Odara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ọmọde ko ma nsun fọnfọn O mu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde o sinjẹki awọn omode tobi, osi nmu wọn dan nia wọ.

Ẹnyin Abiyamọ, eku afojuba egbogi yi Aran yin letipe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko se mani fun awọn omode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi o wa ni Adugbo rẹ.




Igo kekere rẹ je 2/6d Igo nla je 4/6d

**LILO RẸ:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROS

6, Balogun Street, West, 34, Docemo Street
Lagos Nigeria, Lagos
Phone 22515 Phone 24247


## Omo Amerika kan lo Sorun o bo

Ni ọjọ Aje ni ọsẹ ti o koja ni I j ọ b a Amẹrika ran John Glenn lọ si Ọrun. Ninu irin ajo rẹ ni ofurufu o yi aiye ka ni ẹmẹta o de Kano ni iṣẹju kokanlelogun lẹhin ti o ti kuro ni Amẹrika.

Nisiyi John Glenn di ajitannawo nitori e w u nla ni wa aja ti o bọ ilə ẹkun.

### EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TI O WA NI OJU EWE KẸTA

(1) Nilu Rabah, Ilu kekere kan ni Ipinle Sokoto. (2) Lọdun 1918, (3) 1959, (4) Ninu Oṣu-September 1957, (5) Ọlọla Amadu Bello, Sadauna of Sokoto, (6) Oloye Ọbafemi Awolọwọ, (7) Oloye-Festus Okotie Eboh, (8) November 13, 1893, (9) Ile Ẹkọ giga C M S Gramar School (19) Oct 1st 1960


EGBOGI

## 'CHLORODONT'




Bere fun Egbogi Jamani ti o sesẹ dẹ fun ẹnu rirun tabi 'E H I N' ẸNU ti o ba nyọ tabi kika fun ara rẹ,, eyi ni a ma npe ni OMURỌ EHIN. Kokoro ni o ma ngbẹ tabi jẹ idi Erigi Ehin na, a si ma jọ ki ẹnu ma run tabı siyọn bibajẹ pẹlu. Pa kokoro buburu yi run patapata nipa lilo egbogi ti wọn npe ni 'CHILORODONT DROPS'

Igo nla:- Silemeje-abọ pere 7/6
Igo kekere:- Silemẹrin pere 4/
OWO ỌKỌ Silekan-abọ (Postage 1/6d)

BERE FUN

## EGBOGI EKUTE



Ojulowo Egbogi ti npa EKUTE bi mọnamọna laini ewu rara fun enia tabi fun ohun ọsin miran ni ile.

Silemeji pere ni (2/-) Dosini (£1)
OWO ỌKỌ:- Silekan-abọ (Postage 1/6d)

Bere Egbogi wọnyi ni ṣobu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe sobu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi orisi omiran funọ o, maṣe gba rara.

# FEDERATION OF NIGERIA THIRD DEVELOPMENT LOAN

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February/March, 1962. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966 - to be repaid in full on 7th June, 1966.

2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986 - to be repaid in full on 7th June, 1986

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

*W. A. TIBBLES.*
*General Manager.*

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.


# Ebi npa mi olose nkiri, nigbati we Inu ngo se we ode

KADUNA:- Niwọn agogo Mọkanla-abọ owurọ a gbọ wipe ọkunrin Hausa Alagbe kan wọ inu kotu nibiti Alikali gbe nṣe idajọ, awọn Ọlọpa gbidanwo lati da duro ṣugbọn Alagbe na ko gba rara, O kato, o si ni agbara awọn Ọlọpa si mu ti.

Nigbati ritiriti rẹ nfẹ da ijoko kotu ru, Adajọ dide o sọ fun awọn awọn Ọlọpa wipe ki nwọn mu ọkunrin oloju kan na wa siwaju on o si wifun wipe, iwọ ni ngo fi ṣe apẹrẹ fun awọn ẹni bi iru rẹ ti o ku, nigbati iwọ mọ wipe, ihinyi ko nṣe oja ti a le fun ọ ni owo ninu ohun ti a nta, sọ fun mi kini iwọ wa ṣe nih'n yi?

Ọkunrin Alagbe na dahun wipe, ẹru re ati ofin rẹ lo ba mi ni mo ṣe mbọ lọdọ rẹ lati fi ọrọ ẹdun mi han ọ ki awọn Ọlọpa to bẹrẹ si di mi lọna. Ọba ko sa sọ pe ki enia mase witi ẹnu rẹ Adajọ sọ pe odara kini ọrọ ẹdun rẹ na?

Alagba na dahun pe, o di ijẹta ti mo ti ri onjẹ jẹ, lana ni mba lọ jale ṣugbọn ẹru rẹ bami, nitorina ni mo ṣe pinu lati wa fi ọrọ na han ọ ki o ba mi wa owo lati fi jeun nisisiyi, ni adajọ ba gbe sisi fun o gba, o kọri si isọ olonjẹ.

# DURO KO OGBO

Ẹniti o ba gbẹkẹle ọrọ rẹ yio ṣubu ṣugbọn olododo yio ma gba bi ẹka Igi.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ẹkọ, o fẹ imọ ṣugbọn ẹniti o korira bawi ẹranko ni.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN PE NI:—

# RICHALET

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara ẹnia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buruku ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.
Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo, Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni ilẹ yi.
Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatanbulu si Itali jẹ. Mọ daju pe bi Ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wonyi le ṣe ọ Lakuregbe, oriṣiriṣi Inarun Ojuṣiṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Aya didun Ianpara ekuru laya.
Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibarudi riro pẹlu egbogi Risaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwo yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-

IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



AKIYESI FUN ENITI O FẸ RA TABI TA ILE TABI ILẸ NI IBI GBOGBO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra tabi tita tabi fifi ile ya, tabi lati haya ile to dara ti o si laye tabi ile iṣẹ tabi ilẹ eyiti ko pọju adọta ẹsẹ ni fifẹ ati ọgọrun ẹsẹ ni gigun, nihin tabi lọhun ati nibi gbogbo, bi Eko, Ebute mẹtta, Apapa Yaba Suru Lere, New Lagos, ati ni Idi Oro, Mushin Isọlọ Raod ati Ikẹja tabi nibikibi, Wa ri Ọgbẹni:-

**J. B. Crownson Odujobi & Sons**

1st floor 16, BAMGBOṢE STREET LAGOS


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, 2Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adeniji 4, Oliyide Street, Odu Abọrẹ MUSHIN.